15. Lọdọ ẹni ti kí iwọ maa ṣọ́ra pẹlu nitori ti o kọ ojú ijà sí iwaasu wa pupọ.

16. Ni àkọkọ jẹ́ ẹjọ mi, kò si ẹni ti o ba mi gba ẹjọ́ rò, ṣugbọn gbogbo eniyan ni o kọ̀ mi silẹ̀: Adura mi ni ki a má ṣe kaa si wọn lọrun. (A.A. 7:60.)

17. Ṣugbọn Oluwa gba ẹjọ mi rò, o si fun mi lagbara; pe nipasẹ mi ki a lè waasu naa ni àwàjálẹ̀, ati pé ki gbogbo awọn Keferi lè gbọ́; a si gbà mi kuro lẹnu kiniun naa. (A.A. 23:11; 2 Pet 2:9.)

18. Oluwa yoo yọ mi kuro ninu iṣẹ buburu gbogbo, yoo si gbà mí dé inu ijọba rẹ ọrun: ẹni ti ogo wà fun lae ati laelae. (Amin.) (Psm 121:7; Rom 11:36.)

19. Kí Priska ati Akuila, ati ile Onesforu. (A.A. 18:2.)

20. Erastu wà ni Korinti: ṣugbọn mo fi Trofimu silẹ ni Miletu ninu àìsàn. (A.A. 19:22.)

21. Sa ipá rẹ lati tètè wa ṣaaju ìgbà òtútù. Eubulu ki ọ, ati Paudani, ati Linu, Klaudia, ati gbogbo awọn arakunrin. (ẹsẹ 9.)

22. Ki Oluwa wà pẹlu ẹ̀mí rẹ ki oore-ọfẹ wà pẹlu yin. (Amin.) (Gal 6:18; Film 25.)

# 56

# TITU

**(A.D. 65)**

## ORI 1.

**Ìkíni.**

PAULU, iranṣẹ Ọlọrun, ati Aposteli Jesu Kristi, gẹgẹ bi igbagbọ awọn ayanfẹ Ọlọrun, ati ìmọ̀ otitọ ti nbẹ gẹgẹ bi iwa-bi-Ọlọrun, (Rom 1:1; 2 Kor 1:1; 1 Tim 2:4; 6:3.)

2. Ninu ireti ìyè ainipẹkun, ti Ọlọrun, Ẹni ti kò lè ṣèké, ti ṣe ileri ṣaaju ipilẹṣẹ ayé; (2 Tim 1:1; Rom 16:25.)

3. Ṣugbọn ni akoko tirẹ̀ o fi ọ̀rọ̀ rẹ̀ hàn ninu iwaasu, ti a fi le mi lọwọ gẹgẹ bi aṣẹ Ọlọrun Olugbala wa; (2 Tim 1:10; 1 Tess 2:4.)

4. Si Titu, ọmọ mi nitootọ́ nipa igbagbọ ti i ṣe ti gbogbo eniyan: oore-ọfẹ, ati alaafia, lati ọ̀dọ̀ Ọlọrun Baba wa ati Kristi Jesu Olugbala wa. (2 Kor 2:13; Ef 1:2; 1 Tim 1:2.)

**Iwa ti o tọ fun awọn alàgbà.**

5. Nitori idi eyi ni mo ṣe fi ọ silẹ ni Krete, ki iwọ lè ṣe ètò ohun ti o kù, ki o si yan awọn alàgbà ni olukuluku ìlú, bi mo ti paṣẹ fun ọ, (A.A. 27:7; 14:23; 11:30.)

6. Bi ẹnikan ba ṣe aláìlẹ́gàn, ọkọ aya kan, ti o ni ọmọ ti o gbàgbọ́, ti a kò fi sùn fun wọbia, ti wọn kò sì jẹ́ alagidi. (1 Tim 3:2–4.)

7. Nitori pe o yẹ ki bisọbu jẹ́ alailẹ́gàn, gẹgẹ bi iriju Ọlọrun; ki o má jẹ aṣe-tinu-ẹni, oninu-fùfù, ọ̀mùtí, aluni, olojukòkòrò; (1 Kor 4:1; Ef 5:18.)

8. Bikoṣe olufẹ alejò ṣiṣe, olufẹ awọn eniyan rere, alairekọja, olootọ́, ẹni mímọ́, ẹni ìwọ̀ntúnwọ̀nsì; (1 Tim 3:2; 2 Tim 3:3.)

9. Ti o ndi ọ̀rọ̀ otitọ mu ṣinṣin eyi ti i ṣe gẹgẹ bi ẹ̀kọ́, ki oun lè maa gba-niniyanju,ninu ẹ̀kọ́ ti o yè kooro, ki o si lè maa dá awọn asọrọ-òdì lẹ́bi. (1Tim 1:19; 1:10.)

**Paulu sọ nipa awọn olukọ èké.**

10. Nitori pe ọpọlọpọ awọn alagidi, awọn asọrọ asán, ati awọn ẹlẹtan ni nbẹ, paapa awọn ti ikọlà; (1 Tim 1:6; A.A. 11:2.)

11. Awọn ẹni ti a nilati pa lẹnu mọ́, awọn ẹni ti nda odidi agbo ilé rú, ti wọn nkọni ni ohun ti kò yẹ nitori èrè àìtọ́. (2 Tim 3:6; 1 Tim 6:5.)

12. Ọkan ninu wọn, ani woli awọn tikarawọn, wi pe, "Èké ni awọn ará Krete nigba gbogbo, ẹranko buburu, olè alájẹkì." (A.A. 17:28.)
13. Otitọ ni ẹ̀rí yìí, Nitori naa, bá wọn wí gidigidi, ki wọn lè yè koro ni igbagbọ: (2 Kor 13:10; Tit 2:2.)
14. Ki wọn má ṣe fiyesi ìtàn lásán ti awọn Ju, ati ofin awọn eniyan ti wọn yipada kuro ninu otitọ. (1 Tim 1:4; Isa 29:13.)
15. Ohun gbogbo nì o mọ́ fun awọn ẹni ti o mọ́, ṣugbọn fun awọn ti a sọ di ẹlẹ́gbin ati awọn alaigbagbọ kò si ohun ti o mọ́; ṣugbọn ati inu ati ẹ̀rí-ọkàn wọn ni o ti dibàjẹ́. (Luk 11:39,41; Rom 14:23.)
16. Wọn jẹwọ pe wọn mọ Ọlọrun; ṣugbọn nipa iṣẹ́ wọn,wọ́n sẹ́ ẹ, wọn jẹ ẹni irira, ati alaigbọran, aláìyẹ fun iṣẹ́ rere gbogbo.(1 Jhn 2:4; 2 Tim 3:5,8.)

## ORI 2.

**Igbe ayé Onigbagbọ laarin ara wọn.**

SUGBỌN iwọ maa sọ ohun ti o ba ẹ̀kọ́ ti o yè kooro. (Tit 1:9.)
2. Ki awọn àgbàlágbà ọkunrin jẹ ẹni ìwọ̀ntúnwọ̀nsì, oníwà-àgbà, aláìrékọjá, ẹni ti o yè koro ní igbagbọ, ní ifẹ, ati ni suuru. (Tit 1:13.)
3. Bẹẹ gẹgẹ ni ki awọn àgbàlágbà obinrin jẹ́ oniwà-mímọ́, ki wọn má jẹ asọ̀rọ̀-ẹni-lẹhin, tabi ọ̀mùtí, bikose olùkọ́ni ni ohun rere; (1 Tim 3:8.)
4. Ki wọn lè tọ́ awọn ọ̀dọ́mọbinrin lati fẹ́ran awọn ọkọ wọn, lati fẹran awọn ọmọ wọn,
5. Lati jẹ́ alairekọja, mímọ́, aṣiṣẹ-inu-ile, ẹni rere, awọn ti ntẹriba fun awọn ọkọ wọn, ki ọ̀rọ̀ Ọlọrun má baa di isọ̀rọ̀-ọ̀dì si. (1 Kor 14:34; Ef 5:22; 1 Tim 6:1.)
6. Bẹẹ gẹgẹ ni ki o gba awọn ọdọmọkunrin niyanju lati jẹ alairekọja.
7. Ninu ohun gbogbo maa fi ara rẹ hàn ni apẹẹrẹ iṣẹ rere: ninu ẹ̀kọ́ maa fi otitọ-inu hàn, ìwà àgbà. (1 Tim 4:12.)
8. Ọ̀rọ̀ ti o yè kooro, ti a kò lè dá lẹbi; ki oju ba lè ti aṣodi-eniyan ni àìní ohun buburu kan lati wí sí wa. (1 Tim 6:3.)
9. Gba awọn ọmọ-ọ̀dọ̀ niyanju lati maa tẹriba fun awọn ọ̀gá wọn, ki wọn maa ṣe ohun ti o yẹ ninu ohun gbogbo; ki wọn má ṣú wọn lóhùn, (Ef 6:5.)
10. Ki wọn má ṣe fẹ́wọ́, ṣugbọn ki wọn maa fi ìwà otitọ rere gbogbo hàn ki wọn lè maa ṣe ẹ̀kọ́ Ọlọrun Olugbala wa ni ọ̀ṣọ́ ninu ohun gbogbo. (Matt 5:16.)

**Wíwo ọ̀nà fun ireti ti o ni ìbùkún.**

11. Nitori oore-ọfẹ Ọlọrun ti farahàn fún ìgbàlà gbogbo eniyan (Rom 5:15; 1 Tim 2:4.)
12. O nkọ́ wa pé, ki a sẹ́ aiwa-bi-Ọlọrun ati ifẹkufẹ ayé, ki a si maa wà ni àìrékọja, ni òdodo, ati ni iwa-bi-Ọlọrun ni ayé isinsinyìí; (Tit 3:3; 2 Tim 3:12.)
13. Ki-a maa wo ọ̀nà fun ireti ti o ni ìbùkún ati ifarahan ogo Ọlọrun wa ti o tobi ati ti Olugbala wa Jesu Kristi; (2 Tess 2:8; 2 Pet 1:1.)
14. Ẹni ti o fi ara rẹ̀ fún wa. lati rà wa pada kuro ninu ẹ̀ṣẹ̀ gbogbo, ati ki o si lè wẹ awọn eniyan kan mọ́ fun ara rẹ̀, fun ìní oun tikalara rẹ̀ awọn onitara si iṣẹ rere. (1 Tim 2:6; Heb 9:14; Eks 19:5; Ef 2:10.)
15. Nkan wọnyìí ni ki iwọ maa sọ, ki o si maa gba-ni-niyanju, kí o sì maa fi aṣẹ gbogbo bániwí. Má ṣe jẹ ki ẹnikẹni o gàn ọ́.

## ORI 3.

**Igbagbọ ati iṣẹ́.**

MAA rán wọn leti lati maa tẹriba fun awọn ìjòyè, ati fun awọn aláṣẹ, lati maa ṣe igbọran, ati mura si iṣẹ rere gbogbo, (Rom 13:1; 2 Tim 2:21.)
2. Ki wọn má ṣe sọ̀rọ̀ ẹnikẹni ni ibi, ki wọn má ṣe jẹ́ onija bikoṣe ẹni pẹ̀lẹ́, ki wọn maa fi ìwà tutu gbogbo hàn si gbogbo eniyan. (Ef 4:31; 2 Tim 2:24,25.)
3. Nitori awa pẹlu ti jẹ òmùgọ̀ ní-

gbàkan rí, alâìgbọran, aṣáko, ẹni ti nsìnrú fun oniruuru ifẹkufẹ ati adùn ayé, ti a nlo ọjọ ayé wa ninu àránkan ati ìlara, ẹni ìríra, ti a si nkóríra awọn ọmọnikeji wa (1 Kor 6:11; 1 Pet 4:3.)
4. Ṣugbọn nigba ti iṣeun Ọlọrun Olùgbàlà wa ati ifẹ rẹ̀ si eniyan farahàn, (Tit 2:11; 1 Tim 2:3.)
5. Ki i ṣe nipa iṣẹ́ ti a ṣe ninu ododo ṣugbọn gẹgẹ bi aanu rẹ̀ ni o gbà wá là, nipa ìwẹ̀nù atunbi ati isọdi-tuntun Ẹmi Mímọ́. (Rom 3:20; Ef 5:26; Rom 12:2.)
6. Ti o dà si wa lori lọpọlọpọ nipasẹ Jesu Kristi Olugbala wa; (Rom 5:5.)
7. Ki a lè dá wa lare nipa oore-ọfẹ, rẹ̀, ki a sì lè sọ wa di ajogún gẹgẹ bi ireti ìyè ainipẹkun. (Rom 3:24; 8:17,24.)
8. Otitọ ni ọ̀rọ̀ naa, emi si nfẹ ki o tẹnumọ nkan wọnyìí gidigidi, ki awọn ti o gba Ọlọrun gbọ lè fi i sọkan lati tẹramọ iṣẹ́ rere, Nkan wọnyìí dara, wọn si ni ere fun eniyan.(1 Tim 1:15; Tit 2:14.)
9. Ṣugbọn yà kúrò ninu ìbéèrè wèrè, ati ìtàn ìran, ati ìjiyàn, ati ìjà nipa ti ofin; nitori pe alâìlérè ati asán ni wọn. (1 Tim 1:4; 2 Tim 2:14.)
10. Ẹni ti o ba ṣe aládámọ̀ lẹ́hìn ìkìlọ̀ ikinni ati ekeji; kọ ọ́; (Rom 16:17.)
11. Ki o si mọ̀ pe iru ẹni bẹẹ ti yapa, o si ti ṣẹ̀, o sì ti dá ara rẹ̀ lẹbi.

**Ọ̀rọ̀ ikẹhin ati Oore-Ọfẹ.**

12. Nigba ti mo bá rán Artema si ọ, tabi Tikiku, yara tọ̀ mi wa ni Nikopoli nitori ibẹ̀ ni mo ti pinnu lati lo àkókò òtútù. (A.A. 20:4; 2 Tim 4:9,10.)
13. Pèsè daradara ni kiakia fun Sena amòfin ati Apollo lọ́nà àjò wọn, ki ohunkohun má ṣe kù wọn kù. (A.A. 18:24.)
14. Jẹki awọn eniyan wa pẹlu kọ́ lati maa ṣe iṣẹ rere lati lè maa rannilọwọ fun ohun ti a kò lè ṣe aláìní, ki wọn má bàa jẹ́ aláìléso. (ẹsẹ 8.)
15. Gbogbo awọn ti nbẹ lọdọ mi ki ọ. Ki awọn ti o fẹ́ wa ninu igbàgbọ́. Ki oore-ọfẹ wà pẹlu gbogbo yín. (Kol 4:18.)

57

# FILEMONI

**(A.D. 64)**

ORI 1.

**Ìkíni.**

PAULU, òndè Kristi Jesu, ati Timoteu arakunrin wa, si Filemoni olufẹ ati alábáṣiṣẹ́ wa ọwọn. (Ef 3:1; 2 Kor 1:1; Filp 2:25.)
2. Ati si Affia arabinrin wa, ati si Akipu ọmọ-ogun ẹlẹgbẹ́ wa, ati si ijọ inu ile rẹ̀. (Kol 4:17; Filp 2:25; Rom 16:5.)
3. Oore-ọfẹ ati alaafia si yin, lati ọdọ Ọlọrun Baba wá, ati Jesu Kristi Oluwa.

**Ifẹ Paulu si Filemoni.**

4. Emi ndupẹ lọwọ Ọlọrun mi nígbàgbogbo, emi nṣe iranti rẹ ninu adura mi (Rom 1:8,9.)
5. Bi mo ti ngbọ́ ti ìfẹ́ rẹ ati igbàgbọ́ ti iwọ ni si Jesu Oluwa, ati si gbogbo awọn eniyan mímọ́; (Ef 1:15; Kol 1:4.)
6. Ki idapọ igbagbọ rẹ lè lagbara, ni ìmọ̀ ohun rere gbogbo ti nbẹ ninu yin si Kristi.
7. Emi saa ni ayọ̀ pupọ ati ìtùnù nitori ifẹ rẹ, nitori ti a tu ọkàn awọn eniyan mímọ́ lara lati ọwọ rẹ wá, arakunrin. (ẹsẹ 20; 2 Kor 7:13.)

**Ẹ̀bẹ̀ Paulu fun Onesimu.**

8. Nitori naa, bi mo tilẹ̀ ni ìgboyà